safe2choose.org

# ÌṢẸ́YÚN ONÍSÈGÙN PẸ̀LÚ MIFEPRISTONE ÀTI MISOPROSTOL

Àlàyé yìí wúlò fún oyún ṣíṣẹ́ pẹ̀lú ògùn fún oyún ọ̀ṣẹ̀ mókànlá tàbí èyítí kò tó bée tí o bá kàá láti ọjọ́ àkọ́kọ́ tí o rí ǹkan oṣù rẹ gbẹ̀yìn

## ÈÈWỌ̀ ÒGÙN OYÚN ṢÍṢẸ́

Ògùn ìṣẹ́yún kò léwu fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn obìnrin, àmọ́ àwọn èèwọ̀ kan wà tí o ní láti mọ̀ kí o tó lo ògùn oyún ṣíṣẹ́

**A KÒ gbà ọ́ níyànjú láti lo Mifepristone àti Misoprostol tí:**

- O bá ń lo **anticoagulants** (ògùn amúèjẹ̀tírín) bíi Heparin àti Warfarin
- O **bá ní àrùn ẹ̀jẹ̀** bíi Porphyria;
- Tí èyà ara **ìkíyèsára rẹ (adrenal gland)** kò bá ṣiṣẹ́;
- Tí Mifepristone, Misoprostol tàbí prostaglandin **kò bá bá ọ́ lára mu**; tàbí
- Tí o bá lóyún **inú egungun** (tí kò sí nínú ilé ọmọ)

Lílò ògùn oyún ṣíṣẹ́ fún oyún inú egungun kò ní pa ọ́ léwu, **àmọ́ kò ní ṣẹ́ oyún náà,** o sì ní láti **kàn sí elétò ìlera-**

**A KÒ gbà ọ́ níyànjú láti lo Mifepristone tí:**

- **O bá ti ń lo steroids bíi** prednisone tàbí dexamethasone láti ọjọ́ pípẹ́

Àmọ́, o lè fi **Misoprostol** nìkan ṣẹ́ oyún

**Tí o bá ní IUD (ọ̀pá ìfètò sọ́mọ bíbí) lára, kìí kúkú ṣe èèwọ̀ fún ọ láti lo ògùn oyún ṣíṣẹ́, àmọ́:**

- ìjàmbá pé oyún inú egungun lo máa ní pẹ̀lú IUD pọ̀ gidigidi
- ó ṣeé ṣe kí inú rírun fẹ́ẹ̀ ṣe ti ẹ ta
- yíyọ IUD kí o tó lo ògùn oyún ṣíṣẹ́ yóò jẹ́kí ìṣẹ́yún náà lọ láìléwu

## ÌWỌN TÍ A FI ỌWỌ́ SÍ FÚN OYÚN ṢÍṢẸ́ PẸ̀LÚ MIFEPRISTONE ÀTI MISOPROSTOL

- Igba mílígírámù **ẹyọ Mifepristone kan**
- Irinwó mílígírámù ibuprofen* **ẹyọ méjì**
- Igba míkírógírámù Misoprostol** **ẹyọ mẹ́rin sí mẹ́jọ**

*Kàn sí àwọn olùbánidámọ̀ràn wa láti sọ̀rọ̀ lórí ǹkan mírán tí o lè lò tí ibuprofen ò bá bá e lára mu.
**O lè rí àwọn ògùn yìí ní èyà tàbí ìrísí mírán ní orílè-èdèmíràn.

**1** Gbé **ẹyọ Mifepristone kan** (igba mílígírámù) mì pẹ̀lú omi

**Dúró fún wákàtí mẹ́rìnlélógún sí méjìdínláàdọ́ta**

**2** Lo **ẹyọ ibuprofen* méjì** (ọ̀kọ̀ọ̀kan jẹ́ irinwó mílígírámù)

**Dúró fún wákàtí kan**

**3** Fi **ẹyọ Misoprostol mẹ́rin míràn** (ọ̀kọ̀ọ̀kan jẹ́ igba míkírógírámù) sábẹ́ ahọ́n (nínú ẹnu)

Fi sábẹ́ ahọ́n fún **ọgbọ̀n ìṣẹ́jú kí** o tó gbé èyítí ó kù lénu mì pẹ̀lú omi

**4** Fi **ẹyọ Misoprostol mẹ́rin míràn** (ọ̀kọ̀ọ̀kan jẹ́ igba míkírógírámù) sábẹ́ ahọ́n (nínú ẹnu).

Fi sábẹ́ ahọ́n fún **ọgbọ̀n ìṣẹ́jú kí** o tó gbé èyítí ó kù lénu mì pẹ̀lú omi

**A gbà ọ́ níyànjú gidi gidi láti lo ẹyọ Misoprostol mẹ́jọ.** Tí o kò bá rí tó ẹyọ Misoprostol mẹjọ, o lè yàn láti tẹ̀síwájú pẹ̀lú ẹyọ mẹ́rin péré, àmọ́ iṣẹ́ rẹ̀ le má pèé, pàápàá jùlọ tí oyún rẹ bá ti tó ọ̀ṣẹ̀ mẹ́wàá sí mẹ́tàlá.

## ÀWỌN ÀBÁJÁDE TÍ Ó LE JẸYỌ LÁTÀRÍ LÍLO ÒGÙN ÌṢẸ́YÚN

Léyìn tí wón bá lo Mifepristone, àwọn obìnrin díẹ̀ yóò rí àwọn àmì àilera, àmọ́ léyìn tí wón bá lo Misoprostol, àwọn obìnrin kan yóò rí **àwọn àbájáde wọnyí fún wákàtí bíi mélòó kan**



Orí fífọ́ — Ibà — Òòyì/Èébì — Òtútù — Ìgbẹ́ gburu

## ÀKÓJỌ ÀWỌN ÀMÌ ÌKÌLỌ̀ NÌGBÀTÍ O BÁ Ń FI ÒGÙN SẸ́YÚN

Tí o bá ní ọ̀kan nínú àwọn àmì àìlera wọ̀nyí Ó ṣeé ṣe kí o máa ní ìlọ́ọ̀lú O sì nílò láti tọ **oníwòsàn** rẹ lọ lójú ẹsẹ̀

- **Ẹ̀jẹ̀ tí ó ń dà kọjá àyè**

  Àwọ̀tẹ́lẹ̀ ǹkan oṣù méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ tí ó kún (tíwájú tẹ̀yìn) láàrín wákàtí kan

  Tí ó fi tó **wákàtí méjì àbí jù bẹ́ẹ̀ lọ**



- **Ara gbígbóná ìwọ̀n Celsius méjìdínlógóji tàbí ọgọ́rùn-ún ó lé bíntín Farenheit**

  Ara gbígbóná tí kò wálẹ̀ lẹ́yìn tí o lo ibuprofen (tàbí àwọn ògùn ìdènà ìnira míràn)

  Tí ó tó **wákàtí mẹ́rìnlélógún lẹ́yìn** tí o ti lo ògùn ìṣẹ́yún náà

  Rí̀i dájú wípé o lo **ẹ̀rọ àyẹ̀wò gbígbóná tàbí tútù**




- **Ẹ̀jẹ̀ tí ó yàtọ̀ sí ti ǹkan oṣù rẹ**

  Ẹ̀jẹ̀ tí ó ní àwọ̀ tàbí òórùn míràn




- **Àmì pé kò bá ọ lára mu**

  Ọwọ́, ọrùn àti/tàbí ojú pípọ́n, yíyún tàbí wúwú Ìnira láti mí, kódà lẹ́yìn tí o lo ògùn tí ó le jẹ́kí o mí dáadáa



## ÀWỌN ÌṢỌ́RA LẸ́YÌN TÍ O BÁ LO ÒGÙN ÌṢẸ́YÚN

Láàrín ọ̀sẹ̀ bíi mélòó àkọ́kọ́ lẹ́yìn tí o fi ògùn ṣẹ́yún títí ẹ̀jẹ̀ dídà rẹ yóò fi dínkù sọ́ra fún àwọn ǹkan wọ̀nyí **láti dènà àrùn ẹ̀jẹ̀ àti/tàbí àkóràn**

**✖ Yẹra fún fífi ǹkan bọ ojú ara rẹ**



Àwọ̀tẹ́lẹ̀ ǹkan oṣù tí wọ́n má ń bọ abẹ́



Àwọ̀tẹ́lẹ̀ ǹkan oṣù tí ó dàbí ike ìmomi

**✖ Yẹra fún iṣẹ́ àṣekára**



Ṣíṣe eré ìdárayá



Gbígbé, títì tàbí fífa ǹkan wúwo




Rírìn kọjá àyè



Gígun àkàsọ̀ tí ó pọ̀jù



## TẸTÍ SÍ ARA RẸ ÀTI ÌFẸ́ INÚ RẸ

O lè bẹ̀rẹ̀ ìbálòpọ̀ nígbàkúùgbà tí o bá ti lérò wípé ó tọ́ fún ọ, àmọ́ a gbà ọ níyànjú **láti dúró títí ẹ̀jẹ̀ dídà náà kò ní pọ̀ mọ́**

**Láti dènà oyún àìfẹ́ lọ́jọ́ iwájú,** ọ̀nà ìdènà oyún seé lò nítorí o tún le loyún míràn lẹ́yìn ọjọ́ mẹ́wàá tí o lo ògùn oyún ṣíṣẹ́.

## BÍ O ṢE LE MỌ̀ BÍ OYÚN NÁÀ BÁ ṢẸ́

**Àyẹ̀wò ìtọ̀(HCG)**

- Ó seé ṣe nílé
- **Ó má ń ṣe déédé ní ọ̀sẹ̀ mẹ́rin** lẹ́yìn ìgbàtí o lo ògùn ìṣẹ́yún



**Àyẹ̀wò ẹ̀jẹ̀ (HCG)**

- Ó nílò à ń lọ sí ilé ìwòsàn
- **Ó má ń ṣe déédé ní ọ̀sẹ̀ mẹ́rin** lẹ́yìn ìgbàtí o lo ògùn ìṣẹ́yún



**Àkíyèsí:** ó dára tí o bá tún lo àyẹ̀wò ẹ̀jẹ̀ tí o lò kí o tó lo ògùn ìṣẹ́yún láti le sàfiwé àwọn atọ́ka oyún

**Àyẹ̀wò ilé ọmọ**

- Ó nílò à ń lọ sí ilé ìwòsàn
- **Ó má ń ṣe déédé ní ọ̀sẹ̀ mẹ́rin** lẹ́yìn ìgbàtí o lo ògùn ìṣẹ́yún



**Àkíyèsí:** tí o bá ṣeé kí ó tó pé ọ̀sẹ̀ méjì lẹ́yìn ìgbàtí o lo ògùn ìṣẹ́yún ẹ̀jẹ̀ àti àwọn ẹ̀rúnrún le hàn nínú àyẹ̀wò náà àwọn òṣìṣẹ́ ilé ìwòsàn le wípé “oyún rẹ kò ṣẹ́ tán” wọ́n sì le gbà ọ́ níyànjú láti ṣe àwọn ètò tí kò wúlò.

▶ **Rántí wípé yóò gbà ọ ní àárín ọ̀sẹ̀ méjì láti ṣẹ́ oyún pẹ̀lú ògùn**

safe2choose

**Fún àlàyé síwájú síi àti ìrànlọ́wọ́, kàn sí àwọn olùbánidámọ̀ràn lórí ọ̀rọ̀ ìṣẹ́yún pẹ̀lú ìfiwéránṣẹ́ orí afẹ́fẹ́ ní info@safe2choose.org tàbí pẹ̀lú ìtàkurọ̀sọ ààyè ni safe2choose.org/yo.**